# Irohin Yoruba

NO. 825. | MARCH 29 — APRIL 4, 1961 | KOBO MEJI (2D)


### Lakaye Ọrọ

NIGBANA ni mo wo gbogbo iṣẹ Ọlorun, pe enia ko le ridi iṣẹ ti a nṣe labẹ ọrun nitoripe bi enia tilẹ gbiyanju ati wadi rẹ, sibẹsibẹ ki yio le ri i, ati pẹlupẹlu bi ologbọn enia ro lati lati wadi rẹ, sibẹ ki yio le ridi rẹ.





O dara pupọ fun Ikọ ti o nyọ awọn ẹbi rẹ lẹnu

O wa fun tita kakiri Ile-egbogi


# HALLELUYAH! JESU KRISTI J-I-N-D-E!



## Awọn ọmọ ẹhin "Jesu" Oyingbo fẹ ba a ṣẹjọ

**Ninu iwe 'Irohin Yoruba wa ọsẹ ti o kọja, loju ewe kẹrindinlogun, a sọ gẹgẹbi Immanuel Olufunmilayọ Odumosu, ti gbogbo enia mọ orukọ rẹ ni 'Jesu Oyingbo' ti ṣe ko sinu pakute awọn Ọlọpa inu ti nwọn si ti pee fun ibere ọrọ lọwọ rẹ. *A kọ* sinu iwe wa na pe ọrọ na koi ti i pari. Ohun ti a rigbọ lọsẹ yi nipe ninu awọn ọmọ ẹhin rẹ ti pinnu lati baa ṣe ẹjọ ni kotu Ijọba. A gbọ pe 'Jesu Oyingbo' paapa ko dakẹ.**

...ati ọsẹ ti o kọja na ni asoju iwe irohin wa ti nsa agbara lati ri "Jesu Oyingbo" ki o le gbọ ti ẹnu rẹ t'o ku lati sọ, ṣugbọn okunrin na ko ṣe e ri, dipo ki enia le ri, nṣe ni nwọn ha ilẹkun ile rẹ ni Somolu Onipanu lọna Titi Opopo Ikorodu.

Gẹgẹbi a ti rohin ninu iwe wa ti ọsẹ to kọja, awọn ti nwọn mu ẹsun rẹ wa siwaju awọn ọlọpa'nu ni awọn igi-lẹhin ọgba rẹ mẹta ti orukọ wọn njẹ David Oluwọle (Biṣọpu") Olufẹmi Oluṣọla ati Afọlabi Oluṣina.

### "IJỌ ATUNBI"

Ejọ kanna ti awọn ogunna-gbongbo ninu agbo "Jesu Oyingbo" yi ro fun awọn ọlọpa ni nwọn sa ntẹnu mọ fun gbogbo awọn to wa sọdọ wọn lati wadi nipa ọrọ na. Ṣugbọn nigbati aṣoju iwe irohin wa de ọdọ ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ adamọdi "Jesu" yi, o sọ nipa iwa ti "Jesu Oyingbo" na nhu si awọn ọmọ agbo rẹ, o si tun sọ nipa ẹgbẹ kan ti adamọdi "Jesu" yi da silẹ ti njẹ "Ijọ Atunbi ti Jesu Oyingbo' (Regeneration Group)

Ogbẹn ti o sọ nipa ẹgbẹ yi fun aṣoju iwe wa ni gbẹnagbẹna kan ti orukọ rẹ njẹ Joseph Oyebola ti o ngbe ilu Itirẹ lẹba Mushin. O sọ pe lati nkan bi ọdun mẹta sẹhin ni on ti wa ninu 'Ijọ Atunbi' yi on paapa si pẹlu awọn ti o nda idamẹwa owo fun "Jesu Oyingbo". O ni owo dida na ki iṣe afagbara da, o ni ṣugbon olukuluku awọn sa nda owo na bi "Jesu Oyingbo" ti paalaṣẹ fun awọn ni.

### IṢẸ LAISI OWO

O ni ọkan 'nu ohun o mu on kuro ninu 'Ijọ Atunbi' yi (Regeneration Group) ni-

(Wo oju ewe keji)

## Kayọde yaju si Gomina

OLOYE J. A. O. Ọdẹbiyi, aṣiwaju Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, ti i si iṣe Minista Alamojuto Eto Inawo Ijọba Ipinlẹ na mu ẹsun Ọgbẹni R. A. Fani-Kayọde, Alaga Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) Ẹka Ipinlẹ Iwọ-Orun ati Aṣiwaju Ẹgbẹ Alatako ninu Igbimọ Ijọba Ipinlẹ na, wa siwaju Igbimọ Ijọba na ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi pe o hu iwa afojudi ati abuku si Ọba Alaiyeluwa Ọlọla Adesọji Aderemi, Ọni Ifẹ ti iṣe Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun.

Iwa afojudi na ṣẹlẹ ki nwọn to bẹrẹ ipade Igbimọ Ijọba na. Bayi ni ọrọ na si lọ. Gẹgẹbi aṣa ati eto ki-ipade na to bẹrẹ, Oloye S. L. Akintọla, ti iṣe Alakoso Ijọba ni lati fi awọn enia pataki-pataki ninu awọn aṣoju Igbimọ na han Gomina. Gomina na yio ki olukuluku ni kọọkan, awọn na yio si da a lohun lọkọọkan pẹlu ọwọ ati itẹriba.

### IWA ABUKU

Ninu awọn ti Gomina na ni lati ki ni Ọgbẹni Fani-Kayọde wa. Ni ọjọ na, ẹgbẹ Oloye Ọdẹbiyi ni o si duro si. Bi Gomina ti nki awọn enia wọnyi bọ ti o si ku sata ki o de ọdọ Ọgbẹni Fani-Kayọde ni ẹruku ba yẹra, o ni on fẹ de ile iyagbẹ. Bẹni o ti ṣe kuro ni ipo rẹ ti o ti duro si tẹlẹ ri, nwọn ko si tun ri i mọ titi ipade Igbimọ na fi bẹrẹ.

Irufẹ iwa abuku si Gomina bayi bi ọpọlọpọ awọn enia to wa nibi eto ẹyẹ ọjọ na ninu, nigbati nwọn si de ibi ipade, ni Oloye Ọdẹbiyi ba fi mu ẹsun rẹ wa pe ki ipade na gbe ọrọ na yewo. Ṣiwaju ki Oloye Ọdẹbiyi to sọrọ, Ọgbẹni J. O. Awopeju, ọkan ninu awọn aṣoju Igbimọ Ijọba na ti f'ẹnu ba ọrọ Ọgbẹni Fani-Kayọde, o si rohin gẹgẹbi o ti ṣe ta abuku fun Gomina wọn.

Oloye Ọdẹbiyi tun ṣe alaye pe ki Gomina to de ọdọ awọn fun kiki,- Ọgbẹni Fani-Kayọde ti tọrọ aye lati lọ si ile iyagbẹ, o ni on si gba a ni imọran pe ki o mu suru titi yio fi kan an lati fi han Gomina, ṣugbọn o kọ jalẹ lati gba imoran on, o si kuro ni aye rẹ ki Gomina to de ọdọ rẹ.

Nigbati awọn ti o mu ẹsun Ọgbẹni Fani-Kayọde wa siwaju Igbimọ ti sọrọ

(Wo oju ewe kẹkanla)

Irohin Yoruba

## ỌRỌ-OLOTU

# KABỌ ỌJỌ RERE.

Alleluiah! Alleluiah!! Alleluiah!!!
Iia d'opin ogun si tan
Olugbala jagun molu
Orin ayọ l'a o ma a ko. Alleluiah

Ni ọjọ marun l'oni, ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ keji oṣu kẹrin odun yi (oṣu ti a o bọ si yi) ni gbogbo Kristieni ti o wa yika gbogbo agbaiye yio ṣe ajọdun Ajinde Jesu Kristi. Ẹniti awọn Juu ṣe inunibini si ti nwọn si kan an mọ agbelebu, ti o si ku, ti o si jinde kuro ninu oku ni ọjọ kẹta.

Kini anfani Ajinde yi jẹ fun awọn Kristieni? Anfani ti Ajinde Jesu Kristi jẹ fun awọn Kristieni ni wipe: nwọn ni ibiti opin iṣẹ wọn ninu Igbagbọ yio gbe yọri si. Nitori Paulu Aposteli sọ wipe, "Bi o ba ṣe pe kiki aiye yi nikan ni awa ni ireti ninu Kristi, awa jasi otosi julọ ninu gbogbo enia" "Nitoripe bi a ko ba ji awọn oku didẹ njẹ a ko ji Kristi dide". Bi a ko ba si ji Kristi dide, asan ni Igbagbọ nyin". "Bi Kristi ko ba si jinde, njẹ asan ni iwasu wa, asan si ni Igbagbọ nyin" "Njẹ nisisiyi Kristi ti jindẹ kuro ninu oku, o si di akọbi ninu awọn ti o sun".

Orọ ayọ na de
Olugbala bori
O fi boji silẹ
Bi Olodumare
A digbekun ni 'gbekun lọ
Jesu ti o ku di alaye

### ILE ỌBA TI O JO ẸWA NI O BU KUN UN

Nigbati o ku ọsẹ kan ti ajinde yi ṣẹlẹ, gbogbo enia bẹrẹ si i ke Hosannah! Hosannah!! Hosannah!!! niwaju ati lẹhin Jesu nigbati o gun kẹtẹkẹtẹ wọ Igboro Jerusalẹmu. Nwọn nwipe Hosannah fun ọmọ Dafidi, Olubukun ni ẹniti mbọ wa li orukọ Oluwa. Ẹyẹ ati iyin ti wọn fun Jesu na ga pupọ ti o fi dabi ẹnipe ki nwọn ma a ṣe bẹ fun un ni gbogbo igba.

Nigbati awọn Farisi ati awọn Sadusi ri ẹyẹ ti nwọn ṣe fun Jesu yi inu bi wọn, nwọn si nfẹ iparun rẹ lesẹkẹsẹ, nitorina nwọn wa ẹjọ si i lẹsẹ nwọn si ko awọn ẹlẹri eke jọ fun ẹsun pe o mba ọjọ isinmi jẹ nipa ṣiṣe iwosan awọn alaisan ni ọjọ isinmi ati pe o npe ara rẹ ni Ọmọ Ọlọrun o si tun pe ara rẹ ni Ọba awọn Juu.

Nigati Pọntiu Pilatu yẹ ẹjọ rẹ wo, o ni on ko ri ẹbi li ọwọ rẹ ṣugbọn awọn Juu ni ki o sa da lẹbi pe o jẹbi iku, nwọn si nkigbe wipe, kan an mọ agbelebu! kan an mọ agbelebu!! kan an mọ agbelebu!!! Nigbati Pilatu tẹnu mọ ọ wipe ko jẹbi iku, nwọn ni ki ẹjẹ rẹ ki o wa si ori awọn ati si ori awọn ọmọ ọmọ awọn, iya na si tale awọn Juu titi di oni oloni yi.

Ẹ kiyesi i pe ẹnu ti nwọn fi ke "Hosannah" kanna ni nwọn tun fi ke "Kan an mọ agbelebu" nitorina ẹ jẹki a ṣọra fun aiye nigbati nwọn ba npọnni ti nwọn ba nyẹnisi, ki a mọ pe iwa ika ati idaniloro mbẹ ni ikun nwọn, ṣugbọn Jesu ti sọ asọtẹlẹ fun awọn ọmọ ẹhin rẹ pe, awọn Juu yio ṣe inu-ni-bini si on de oju iku, ṣugbọn on yio jinde ni ọjọ kẹta.

### Ẹ TUJU KA, MO TI ṢẸGUN AIYE

Nigbati nwọn mu Jesu, ti nwọn da a ni ẹbi iku, ti nwọn na a, ti nwọn gbe ade ẹgun le e lori, ti wọn fi ṣe orisirisi ẹsin ati ẹlẹya, nwọn ro pe awọn ṣẹgun rẹ nigbati o ku lori agbelebu, bi Jesu ti njoro lori agbelebu ni o nsọrọ ifẹ jade lẹnu pe "Baba dariji wọn nitori ti nwọn ko mọ ohun ti nwọn nṣe" nigbati yio dakẹ, o ni baba ni ọwọ rẹ ni mo fi ẹmi mi le, okunkun si ṣu bo aiye aṣọ iboju Tẹmpili si faya, nigbayi ẹru ba awọn ọmọ-ogun ti o duro sibẹ.

Ibanujẹ de ba awọn ọmọ-ẹhin rẹ, nwọn ro pe eyi ni opin gbogbo laala ti nwọn ti nṣe tẹlẹ lẹhin, ṣugbọn nigbati o di ọjọ kẹta owurọ ayọ na de Jesu jinde kuro ninu oku, irohin kan awọn ọmọ-ẹhin rẹ pe Oluwa jinde, o si ni ki nwọn lọ pade on ni Galili. Nwọn si kun fun ayọ ati orin ajinde pe:—

"Kabọ ọjọ rere l'a o ma wi titi
A ṣẹtẹ 'ku loni, ọrun di tiwa
'Wo oku d'alaye, Ọba tit'aiye.
Gbogb'ẹda rẹ Jesu ni nwọn njuba rẹ.
Kabọ ọjọ rere l'a o ma wi titi
A ṣẹtẹ 'ku loni, ọrun di tiwa.

Ẹ ku ewu ọdun o. Aṣeyi ṣamọdun o.

# JESU OYINGBO

Lati oju ewe kini

pe gbogbo iṣẹ ti awọn nṣe, aṣe-igbowo ni, o ni bi ẹnikan ba si ni aiya ti o ba bere pe kini ṣe ti awọn ko ni fi ma a gba owo fun iṣẹ ribiribi ti awọn nṣe yi, o ni "Jesu Oyingbo" yio si da oluwa rẹ lohun pe: "Ẹlẹṣẹ ni i ku", ati pe "gbogbo awọn ọmọ Ijọ Atunbi ko ni tọ iku wo rara".

O ni ohun ti o ya on lẹnu nipe ọpọlọpọ ninu awọn ọmọ ẹgbẹ na lo ti ku, ti "Jesu Oyingbo" yi ko si le ṣe e ki nwọn ma ku, bẹẹ si ni on ni i ma a leri pe on ti sọ awọn di "ẹni atunbi" ti ki yio tọ iku wo mọ lailai!

Ọgbẹni Joseph Oyebọla tun sọ pe ọpọlọpọ iṣẹ ni "Jesu Oyingbo" yi da silẹ, ti ogunlọgọ awọn ọmọ ijọ rẹ si da owo sinu awọn iṣẹ na, ti nwọn si nlọ dara-dara. O ni ṣugbọn awọn ki i mọ bi owo awọn ti nlọ si, o ni "Jesu Oyingbo" ki i si fun ẹnikẹni ninu awọn ni kọbọ lara iye ti owo awọn pa.

### ẸSẸ SI ỌLỌRUN

O ni ohun pataki ti o mu on kuro ninu ijọ na nipe "Jesu Oyingbo" ti yi orukọ rẹ pada, o si sọ ara rẹ ni "Ọlọrun" (Lord). O ni on mọ pe eyi jẹ ohun ilodi ati afojudi si Ọlọrun, ati pe ẹṣẹ nla-nla ni eyi jẹ si Olodumare.

O ni ohun miran ti o tun mu on kuro 'nu ijọ na nipe lati igbati on ti nka nipa orisirisi ẹsun ti nwọn nko sinu iwe irohin nipa "Jesu Oyingbo" yi, o ni ko fesi si ọkankan ninu awọn ẹsun na, bi irọ ni nwọn npa mọ on tabi otitọ ni nwọn nso nipa on. O ni on mọ pe ni ọjọ kan oṣunwọn "Jesu Oyingbo" yio kun, o ni nitorina, ẹsun ti nwọn ka mọ o lẹsẹ lọdọ awọn ọlọpa 'nu ko ya on lẹnu rara.

A gbọ pe nwọn ṣi wa lẹnu ọrọ na. Bi ọrọ na ba ti ṣe nlọ si, a o ma a tun jẹ ki awọn onkawe wa gbọ.

# Akiyesi awọn awo Irawọ nipa ọjọ-ibi

AWỌN nkan wọnyi ni yio ṣẹlẹ larin ọsẹ yi:—

### CAPRICORN
(Dec. 23-Jan. 20)

Iwọ yio ri ayipada ninu iṣẹ rẹ. Ṣe lakaye, ire yio si ri aye lati tun igbesi-aiye rẹ ṣe dada laseko yi.

### AQUARIUS
(Jan. 21-Feb. 19)

F'arabalẹ ki o to ṣe ohunkohun. Bi o ko ba f'arabalẹ, iwọ yio jẹ ki aseko rere ti o fẹ de si ọ fo ọ.

### PISCES
(Feb. 20-Mar. 20)

Ninu osẹ yi, maṣe joko sile pupọ, anfani rẹ wa [illegible] ati lọdọ awọn ara ode. Alafia yio wa fun ọ pupọ laseko yi.

(Wo oju ewe kejila)


Mama fun mi ni



AMAMA ni ojojumọ

AMAMA

O NJẸKI NGNI AGBARA ATI ILERA

NI NAIJIRIA NI A TI ṢE AMAMA

AWỌN ALAGBATA RẸ NI: GLAXO—ALLENBURYS (NIGERIA) LTD. P. M. B. 2310, LAGOS, ati pẹlu ni ABA ati KANO.

**ỌRỌ AKEWI : Lati ọwọ ỌMỌ-ỌBA AKIBU ALARAPE, IBADAN**

# ALUBARIKA L'OJU (10)

OLOTU, karaole o. Gẹgẹ bi aṣoti ọrọ wa, ani, bi ọkọ na ti fọ si ọna meji wa a lẹkanna, bẹni Mofoluwaṣọ pẹlu iya rẹ bọ si apa ọtọọtọ, ti awọn mejeji si bẹrẹsi wo ara wọn lọkankan, titi bẹẹ, ti oju awọn mejeji ko fi tun ri ara wọn mọ larin agbami nla yi.

Bayi ni atẹgun nla yi si gbe olukaluku wọn gba ọna ti o lodi si ara wọn lọ.

Aṣe, bi nkan yi ti nṣẹlẹ gan an fun tiya-tọmọ yi gan an fun tiya-tọmọ yi na gan an ni o tun ṣẹlẹ larin awọn ọmọde mejeji ti igbi-omi tun gbe gba ọna ibomiran bakanna. To bẹ ẹ ti awọn na ko fi tun ri ara wọn mọ loju omi.

### ATẸGUN RỌLẸ

Lẹhin iṣẹlẹ yi ni atẹgun nla na wa bẹrẹsi rọlẹ diędlẹ.

Ọkọ ti Mofoluwaṣọ wa ninu rẹ ni o kọkọ gunlẹ si Erekuṣu kan ni nkan bi oṣu keji, ti afẹfẹ na si bẹrẹsi role.

Bi abala-ọkọ na ti ngunlẹ, bẹni Mofoluwaṣọ dide ti o si bọsi ori ilẹ na. O si wo ọtun, o tun wo osi, ko si ri ẹnikẹni. Ilẹ na si ṣe ajeji loju rẹ to bẹ ẹ gẹ ẹ, ti o fi mbi ara rẹ lere pe, njẹ ara ilẹ ile aiye na ha ni eyi bi?

Mofoluwaṣọ sa bẹrẹsi ṣe ha! pẹlu iyanu kakiri lori ilẹ na ni, o si nrin lọ si oke, o nrin bọsi isalẹ pẹlu iyanu na wipe, ha! ha!! Iru ilẹ wo ni eyi ha jẹ bayi o?

### MOFOLUWAṢỌ DUPẸ

Lori bi ọmọdekunrin yi ti ngba ero wọnyi lọwọ ni ero kan wa si ọkan rẹ wipe, "nigbati mo tilẹ le jaja gunlẹ si ori ilẹ pẹlu alafia nisisiyi, bi o tilẹ jẹ wipe nko le mọ ibiti mo gunlẹ si na rara, sibẹsibẹ na, o tọ fun mi lati fi ọpẹ fun Ọlọrun nipa oreọfẹ Rẹ yi, ani, ti mo tilẹ ṣi fi ẹsẹ tẹ ori ilẹ lati iye ọjọ yi wa. O yẹ ki ndupẹ fun Olọrun."

Bayi ni Mofoluwaṣọ bẹrẹ leti okun na, ti o bu omi, ti o ṣe aluwala. Lẹhinna, o gbe irun duro, o si bẹrẹsi kirun lọ.

Ṣugbọn nkan ti o jẹ iyalẹnu julọ ni wipe, bi ọmọde na ti nkirun lọwọ, nṣe ni o dabi ẹniwipe awọn ọpọlọpọ enia duro lẹhin rẹ ti nwọn si jijọ nki irun na.

To bẹ ẹ, ti o fi jẹwipe, bi ọmọde yi ti salamọ nigbati o pari irun kiki na, bẹẹ ni o gbọ ohun awọn ọpọlọpọ enia ti awọn na salamọ pẹlu rẹ. Eyi mu ki ọmọde na yara bojuwo ẹhin, ṣugbọn ko ri ẹnikankan.

### IYALẸNU NLA

Lẹhin eyi, ọmọde yi bẹrẹsi gba adura, ṣugbọn bakanna ni o tun ngbọ ti ọpọlọpọ enia nṣe amin, amin; ṣugbọn ko ri ẹnikankan rara, eyi si tubọ jẹ iyalẹnu nla fun ọmọdekunrin na, ṣugbọn ko si ohunkohun ti o le ṣe si i.

Bayi ni gbogbo nkan na nlọ titi fun bi ọjọ marun ṣugbọn ohun ti o tun ṣẹlẹ ni wipe, bi ọmọdekunrin yi



AKIBU ALARAPE

* * *

ba ti ronu nipa nkankan lati ri jẹ, bẹni nkan na si njade wa laimọ bi ọrọ na ti jẹ.

Bayi ni Mofoluwaṣọ mba nkan na lọ lori ilẹ ajoji yi fun nkan bi oṣu mẹta. Lẹhin eyi, bi ọmọdekunrin yi ti kirun tan ni irọlẹ ọjọ kan, o si bẹrẹsi ṣe adura gẹgẹbi iṣe rẹ atẹhinwa, bakanna si ni o ngbọ ti ọpọlọpọ enia nṣe amin, amin, laisi ri ẹnikankan.

### ALFA KAN YỌ

Ṣugbọn bi ọmọde na ti npari adura rẹ gẹrẹ, bẹni o ri i ti Alfa kan mbọ ni ọkankan ọdọ rẹ. Eyi si jẹ iyalẹnu nla to bẹ ẹ gẹẹ ti Mofoluwaṣọ ko fi mọ bawo ni eyi ti ṣe ri bẹẹ, o si joko kalẹ loju kanna.

Alfa na si mbọ taara wa si ọdọ rẹ. Nigbana ni ọmọde yi bẹrẹsi ki Alfa na wipe, "ẹ ma a wolẹ o, ẹ ma a rọra o," ati bẹ ẹ bẹ ẹ lọ titi.

Nigbati Alfa na si de ọdọ rẹ, nwọn jijọ ki ara wọn dada. Nigbana ni Alfa na wa bere lọwọ rẹ wipe, "bawo ni idi ọrọ rẹ ti ṣe jẹ, atipe, nibo ni iwọ ro wipe o wa yi?"

Ọmọde na si dahun wipe, "emi ko le sọ ohunkohun nipa idi ọrọ mi, bakanna si ni emi ko mọ ibiti mo wa yi nitoripe, lati ọjọ ti mo ti de Ebute yi em ko ba ẹda enia kan pade ri, bikoṣe loni yi".

Alfa na si dahun wipe, "iwọ ha mọ mi bi?"

### IRANṢẸ PATAKI

Mofoluwaṣọ si dahun wipe, "emi ko mọ nyin rara, ati pe, nigbati o jẹwipe ẹ we lawani bo toju-timu bayi, bawo ni mo ti ṣe le mọ iru ẹniti ẹ nṣe ṣugbọn nkan ti o han si mi nisisiyi nipa iṣesi nyin ni wipe, mo ni ero wipe Alfa nla kan ni ẹ nilati jẹ".

Lẹhin eyi ni Alfa na wa sọ wipe, "bẹ ẹ gan an ni ọrọ na jẹ, atipe, iranṣẹ kan pataki ni mo jẹ lati ọdọ Ọlọrun Ẹlẹda ohungbogbo lati wa fi aṣẹ ati agbara le ọ lọwọ lori ilẹ ajoji yi, Nitoripe, iwọ ni Ọlorun Ẹlẹda ti pese ilẹ na silẹ fun lati igba laili."

(KOI TI PARI O).

## KONGO

(Lati oju ewe kẹsan)

Ghana gbọ irohin na ni nwọn sare lọ gba Lumumba kalẹ lọwọ wọn.

### NKRUMAH TAKU

Nigbati Ọgbẹni Dag Hammerskjoeld gbọ irohin yi, o paṣẹ pe ki nwọn da Lumumba pada fun awọn ọta rẹ kiakia, ṣugbọn Dọkita Kwame Osagiyefo Nkrumah, Olori-ilu Ghana sọ wipe nwọn ko gbọdọ da a pada fun wọn.

Nigbati Nkrumah ko jẹki aṣẹ ti Dag Hammaskjoeld ṣẹ lori Lumumba ṣẹ ni Dag Hammarskjoeld ba binu, o si sọ fun Dọkita Nkrumah pe ki o ṣora rẹ gidigidi.

Dọkita Nkrumah paapa si fi ibinu fun un lesi pe iṣẹ ti o nṣe ki iṣe iṣẹ baba rẹ. Nigbati Lumumba jaja bọ lọwọ awọn ọta rẹ na, inu ile ti Ijọba kọ fun un (State House) ti o kọju si odo Kongo ni o pada si ko si jade kuro nibẹ mọ, gbogbo ipade ti on ati awọn enia rẹ nṣe, ninu Ile na ni nwọn ti nṣe e.

(KOI TI PARI)



# ADAN

faramọ, nitori gbogbo awọn Ijọ na ni ngbadura ni orukọ Jesu Kristi, ti Ọlọrun si ngbọ adura wọn.

ALAPARA—Olotu ẹ ṣe pupọ fun alaye nyin. Ọlorun yio ma a bukun lakaye nyin. Ṣe bi mọ ba ri ọrọ ti o ru mi loju ninu Bibeli mo le bere bakanna?

OLOTU—O le bere eyikeyi ninu ọrọ inu Bibeli, ṣugbọn eyiti mo ba mọ ninu wọn ni ma a ṣe alaye rẹ ni iwọn iba ẹkọ temi ninu Bibeli.

ALAPARA—Mo ri wipe ti mba tun wa si ọdọ nyin nigbamiran ma a wa ma a bere nipa iyẹn. Mo si fẹ ma a lọ na.

OLOTU—Alapara wa ǹa, ma i ti lọ. Mo gbọ ọrọ kan, mo si fẹ wadi lọdọ rẹ bi otitọ ni ọrọ na tabi ahesọ lasan ni.

ALAPARA—Ọrọ nipa kini?

OLOTU—Mo gbọ pe ni ilu awọn Aganin (Ghana) ni Sariyu Rọ-tika-tika tun wa nisisiyi bẹni tabi bẹkọ?

ALAPARA—Ẹ jẹki o di igba miran ti mo ba tun wa ki nwa fun nyin ni esi, nitoripe bi mo ba pe emi paapa ko gbọ bẹ ẹ irọ ni mo pa. O si digba oṣe na. Ẹ ku ipalẹmọ ọdun Ajinde o.

OLOTU—Kabọ o ipade wa bi oyin o.



## BIBELI MIMỌ T'ỌRUN ỌWỌN IṢURA T'EMI

# 'Awọn ami ọjọ ikẹhin'

## Iyan ati ajakalẹ-arun

(Lati ọwọ Evangelist J. J. Akande 1, Ogbomọsbọ.)



Evangelist J. J. AKANDE

AMI kẹta ti a fi mọ pe opin aiye de tan, ati akoko bibọ Jesu sunmọ etile ni eyiti Jesu Kristi sọ ninu Matteu ori 24 ẹsẹ 7, bayi pe, "Iyan ati ajakalẹ-arun, ati iṣẹlẹ yio si wa ni ibi pupọ" Ami kẹta ni Iyan ati Ajakalẹ-arun. Ẹ wo o bi iyan ti mu to laiye isisiyi, ni atijọ, gende ọkunrin ko le jẹ ọka kọbọ kan tan, ṣugbọn lode oni, ẹnikan ṣoṣo njẹ onjẹ ṣile kan ki o to le yo dada.

### ỌRỌ OLUWA

Ni aiye atijọ ni ọpọlọpọ ilu, ẹran ni nwọn nṣa gbaguda fun jẹ, wọn ko mọ ọ jẹ rara, ṣugbọn lode oni yi, iyan ti mu ki gbogbo enia sọ onjẹ ẹran di onjẹ gidi, gari mimu ati ẹba jijẹ di nkan pataki larin ọpọlọpọ enia, iyan lo nṣiṣẹ bẹ.

Nipa ti ajakalẹ- arun, dajudaju ọrọ Oluwa lo nṣẹ mọ araiye lara, bi ẹ ba lọ si ile iwosan ẹ o ri oniruru aisan ti ẹ ko mọ ri, bi o ti pọ to, bi awọn ọlọgbọn aiye ti ngbiyanju to lati ṣe awari oriṣiriṣi egbogi titun fun iwosan oriṣiriṣi arun, bẹni oriṣiriṣi arun titun na tun ngbilẹ siwaju si i.

Bi awọn Dokita ti npọ si i, bẹni awọn alaisan na npọ si i, otitọ ni ọrọ ti a sọ ninu Jeremiah ori 46, ẹsẹ 11, bayi pe, "Li asan ni iwọ o lo ọpọlopọ ogun, ọjaimularada ko si fun ọ". Gbogbo ọgbọn ati ajo awọn ọlọgbọn aiye yi ko le wo araiye san kuro ninu ajakalẹ- arun ti o mba araiye ja, nitoripe ibawi lati ọdọ Ọlọrun ni ajakalẹ-arun na.

Ẹ wo ọpọlọpọ enia ti aisan ṣonpọnna npa, lọdọdun,, ẹ wo ọpọlọpọ awọn ti arun aimọdi npa nigbagbogbo, apẹrẹ wọnyi nran wa leti pe opin aiye yi ku si dẹdẹ.

### IṢẸLẸ BURUKU

Ẹ wo ọpọlọpọ iṣẹlẹ buruku ti o nṣẹlẹ larin awọn enia, nigba miran ẹ o gbọ pe ilẹ ya bo bi ọgọrun enia mọlẹ, gbogbo wọn si ku. Nigba miran ẹ o ma a gbọ pe loru ni odo kun lojiji bo ilu kan mọlẹ ti nkan bi irinwo enia si ṣegbe pẹlu ile ati ẹru wọn. Nigba miran ẹ o gbọ irohin pe oke kan bẹrẹ si fọn okuta ina jade ti yio si pa ọpọlọpọ enia run, ti yio si tun ba ọpọlọpọ nkan jẹ.

Ni atijọ, awọn enia a ma a ni ifọnkanbalẹ lati wọ ọkọ Reluwe (Train) ju moto lọ, nitori ijamba moto, ṣugbọn lode oni nkọ, ẹ'ngbọ nipa ẹgbẹgbẹrun enia ti ọkọ Reluwe npa lọdọdun tabi ẹ ko gbọ?

* * *

Awọn iṣẹlẹ nla-nla igbagbogbo yi nran wa leti pe ọjọ ikẹhin sunmọ etile tan, gbogbo ibiti awọn enia ko nireti ni iṣẹlẹ buburu ti nṣẹlẹ lode oni, dajudaju otitọ ni gbogbo awọn asọtẹlẹ ti Jesu Kristi sọ pe yio ma a ṣẹlẹ nikẹhin aiye.

Nitorina, ẹnyin ọmọ igbala, ami wọnyi ki iṣe fun ijiya aiye nikan ṣugbọn lati le ma a ran wa leti lati le mura silẹ de ọjọ nla Oluwa ti iṣe opin aiye yi. Nitorina ẹ maṣe gbagbe ọrọ ti a sọ ninu Matteu ori 24, ẹsẹ 42, bayi pe, "Nitorina ẹ ma ṣọna, nitori ẹnyin ko mọ wakati ti Oluwa nyin yio de."


# Nikẹhin wayi

## abẹ infarungbọn to mu julọ



1d ni kọbọ




PERE FUN ỌBE ALAFẸFẸ KAN

## Ọbẹ Alafẹfẹ NACET Ọlọni

Trade enquiries to: R. E. HARDING & CO. LTD · LAGOS · ABA · KANO

# ITAN OSUPA (II)

(Lati ọwọ S. L. Ogunniran Ibadan)

**NITORINA, ẹnyin olufẹ ọwọn, ifẹ aiṣẹtan ni mo fẹ, nitori eyi ni mo ro pe yio ṣe wa ni rere. Nitorina, laifa ọrọ yi gun lọ titi, mo fẹ ki oluwarẹ wi jade: Tani ninu nyin ti o le ba mi ku igbati iku ba de. Oluwarẹ ni yio si ṣe ọkọ mi nitori on ni olufẹ atata ti ki i ya ni.**

Nigbati awọn enia wọnyi gbọ ọrọ na tan, idi wọn di omi nitori ko si ẹniti o mọ ninu wọn pe iru ọna bayi ni Oṣupa yo tun ba jade si wọn, gbogbo wọn ko si le fun un ni esi t'o nilari, nṣe ni olukaluku wọn bẹrẹ si sọ pe, "emi ko le ba obinrin ku o, emi ko le ba obinrin ku o", ati bẹẹ bẹ ẹ lọ, gbogbo wọn si tuka laidagbere, o si ku ọgbẹni Ifẹ-otitọ silẹ.

AJAGA IFẸ

Nigbati Oṣupa ri i pe Ifẹ-otitọ ko lọ, o bi i lere pe, "Olufẹ, ṣe ko si nkan ti o ko lọ?" Ifẹotitọ si da a lohun pe, on ni ọrọ lati ba a sọ ni; Oṣupa si gba bẹ ẹ. Ifẹ-otitọ la ẹnu rẹ o si wipe, "Nitotọ ifẹ ni agbara pupọ a si ma a fi ajaga bọ enia li ọrun eyiti o jẹ pe, a ma a ṣoro bọ kuro lọrun ẹni.

"Nigbati agbara ifẹ obinrin ba ru bo enia loju, oluwarẹ a ma a di dọgẹdẹlugbo niwaju obinrin. Bi o tilẹ jẹ pe ifẹ lewu nitotọ, ṣugbọn bi o ba jẹ ifẹ aiṣẹtan, ayọ a ma gbẹhin rẹ. Bi o ba si yori si iku Ọlọrun Ọba A ma a gbe wọn sinu iye ainipẹkun. Nitorina, lati oni yi, mo kọ ile ati ọna mi silẹ, mo gbe ara mi sabẹ itọju rẹ, mo si ṣetan lati ba ọ ku bi iku ba de."

OṢUPA SỌRỌ

Nigbati Oṣupa gbọ ọrọ yi inu rẹ dun pupọ, o si fi tayọtayọ sọ fun Ọgbẹni Ifẹ-otitọ pe, inu mi dun lati gbọ ipinnu rẹ yi. Inu mi yio si dun ju bayi lọ bi o ba le mu ọrọ rẹ ṣẹ. Bi o ba ṣe bi o ti wi yi, emi paapa ṣetan lati ba ọ gbe pọ gẹgẹbi olufẹ ọwọn, ngo si jẹ aya rẹ".

Inu Ifẹ-otitọ dun to bẹ ẹ gẹ e ti o fi sọ ọrọ wọnyi:— "Igbayi ni inu mi dun pupọ, nko si le sọ bi ayọ mi ti pọ to ni asiko yi. Nitotọ, iwọ ifẹ, alagbara, iwọ ti ti mi sihin ati sọhun nipa agbara rẹ. Iwọ ti gbe mi soke, o si ti gbe mi sodo nipa ipa rẹ, iwọ ti daamu ọkan mi, o si ti sọ mi di onirobinujẹ, ṣugbọn ayọ ati ohun rere mbẹ fun oniforiti ati oniparamọ enia. Inu mi dun jọjọ nitori igbayi ni mo to ri ẹhin ọta, awọn ọta ṣubu, fitila okunkun wọn si fọ. Ifẹ ododo si tan imọlẹ rẹ si mi.

(KOI TI PARI)








Işẹ-ọwọ Swiss ti o darajulọ ti a se ni aşa igba isisiyi ti owo rẹ si kere julọ ni a papọ sinu agogo-isomọwọ alami-işowo.

BULER

fun awọn ẹni-ilosiwaju




# Akintọla şi ile işẹ 'Asbestos' ni Ikẹja

IKẸJA.

IROHIN ko to afojuba ni ti aşeyẹ şişi ile işẹ Asbesitọ "Asbestos Cement Products Nigeria Ltd." ni Ikẹja ni ọjọ Abamẹta ti işe ọjọ kẹdogbọn oşu yi. Oloye S. L. Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, ni o şi ile-işẹ na.

Ninu ọrọ rẹ, Oloye Akintọla sọ pe ile-işẹ asbesito oni simẹnti na ni akoko iru rẹ ti yio wa ni Naijiria,, o si ni ero awọn nipa rẹ nipe ki o le şe ilu Naijiria ni anfani.

O ni eyi ki i şe ile-işẹ ti awọn yio kọkọ da silẹ. O si ran ogunlọgọ awọn enia pataki-pataki to wa sibi işile na leti nipa ile-işẹ simẹnti ni Ewekoro eyiti yio ma a şe ẹgbarun ọkẹ tọnnu (200,000 tons) simẹnti.

Oloye Akintọla wa fẹnu ba ọrọ ominira. O ni ominira ti a gba ko le ni igbadun lalaisi işẹ fun olukuluku. O ni eyi wa ninu ero Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun. Nitorina ni Ijọba na şe nsa gbogbo agbara lati ri pe işẹ wa fun gbogbo enia lati ma a şe.

Eto kikọ ile-işẹ na bẹrẹ ninu oşu kejila ọdun 1959, ile-işẹ na yio şi ni agbara lati ma a şe ọkẹ meji ati ma a şe ọkẹ meji ati ẹgbarun tọnnu (48,000 tons) asbẹsitọ oni simẹnti lọdọdun.

Ọgbẹni A. Emsens, alakoso ile-işẹ abesitọ dupẹ lọwọ gbogbo enia to wa sibi aşeyẹ na ati awọn oşişẹ nipa ifọwọsowọpọ wọn eyiti o mu ki ile-işẹ na tete ni ayọrisi rere.

Ki eto ọjọ na to bẹrẹ bi Oloye Akintọla pẹlu awọn alaşẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun to ba wa sibi aşeyẹ na ti joko si aye wọn ni Ọgbẹni A. O. Rewane, Alaga ile-işẹ "Western Nigeria Development Corporation" ti i si şe alakoso ile-işẹ simẹnti titun yi pẹlu ki Oloye Akintọla kuabọ.

## Irawọ

Lati oju ewe keji

### ARIES

(March. 21-April 20)

Bi o ko ba şọ ara rẹ, ohun ti ko tọ si ọ ni yio gba aseko rẹ. Ri i daju pe ohun ti yio şe ọ ni anfani ni o nşe.

### TAURUS

(April 21-May 22)

Maşe jẹki awọn onisọkusọ gbe ọ kọlu awọn enia pataki ti o le şe ọ ni anfani. Jinna si awọn ẹni buburu.

### GEMINI

(May 23-June 21)

Ẹnikan ti o ni ifẹ pupọ si ọ ti iwọ na si ni ifẹ pupọ si yio ko orire ran ọ l'ọsẹ yi.

### CANCER

(June 22-July 22)

Maşe jinna si ohun işoro ti o ba de si ọ, doju kọ ọ, işoro na yio si kuro laipẹ.


Yio fun ọ ni irọrun · ara rẹ yio si ko-giri

. . . Nigbati o ba nwọ bata RỌPỌPỌ —Bata ti a pilẹşe fun igbesẹ kankan fun wiwọ lọsan tabi lalẹ




Bata

Style 35
40s.



Sizes 6-11 (in ½ sizes)

Bata

AWỌN AKANBATA FUN GBOGBO AGBAIYE

Head Office:
81/87 Broad Street, Lagos

Ati ni Ẹka Ile-işe wọn yika Naijiria



# Awọn Ẹgbẹ Onişowo

## *PATERSON, ZOCHONIS & CO. LTD.*

## Ki awọn Ẹgbẹ Onişowo

*ASBESTOS CEMENT PRODUCTS [NIGERIA] LIMITED*

**ku-orire fun aşeyọri Ile-Işẹ wọn ti wọn şi si Ikẹja.**

**Inu awọn Ẹgbẹ Onişowo**

***PATERSON, ZOCHONIS & CO. LTD.***

**si dun si ajumọşe pọ ti nwọn ni ninu idasilẹ Ile-Işẹ titun yi, nipa bayi, nwọn tun fi ọwọ sọ'iya pe awọn ni igbẹkẹle ninu sisọ idasilẹ Işẹ-ọwọ na di ti Naijiria.**


Published by Allied newspapers Limited, Elephant House, 214, Broad Street, Lagos and printed for them by Amalgamated